# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàíjíríà.

**Oṣù Kárùn, Ọdún 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**OṢÙ KÁRÙN, ỌDÚN 2024**

**ÌTÚSÍLẸ̀ TÓ JINLẸ̀ (APÁ KEJÌ)**

1. **Ó ha lè jẹ́ pé mò n'pín**

Nínú ẹ̀jẹ̀ Olùgbàlà?
P'ó kú fémi t'Ó dá lóró,
T'ó lépa Rẹ dójú ikú?
Ìfẹ́ 'yanu! È há tí ṣe,
Tí 'Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

Ìfẹ́ 'yanu! e há tí ṣe,
Tí 'Wọ Ọlọ́run kú fún mi!

2. Ohun 'ìjìnlẹ̀! Ọlọ́run kú!

Taní mọ ìdí ète Rẹ̀?
Lásán l'ángẹ́lì ta kọ́ da,
Nfẹ́ mọ, jìnlẹ̀ ìfẹ́ mímọ́!
Ànú ṣá ni! K'áyé júbà,
Kí ángẹ́lì ma wádì mọ́.

3. O f'ìtẹ́ Bàbá Rẹ̀ sílẹ̀,

Ore-ọ̀fẹ́ Rẹ kò lópin!
Ó bọ́ gbogb' ògo Rẹ̀ sílẹ̀,
Ó kú fún 'ran ọmọ Ádám,
Ànú ṣá ni, láìní ìwọ̀n;
L'Ó wá mi rí, Ọlọ́run mi.

4. Ó pẹ́ ta ti de ẹ̀mí mi,

Ṣinṣin l'ó kun ẹ̀wọ̀n ẹ̀ṣẹ̀;

Ojú Rẹ́ tàn ‘mọ́lẹ̀ ìyè,
Mo tají, túbú sí mọ́lẹ̀;
Ẹ̀wọ̀n mí bó, mo d’omìnira.
Mo dìde, mo sì ntọ̀ lẹ́yìn.

5. Èmi kò jáyà ẹ̀bi mọ́
Tèmi ni Kríst, pátápátá!
Mo yè nínú Olórí mi,
A f’òdodo ọ̀run wọ̀ mí,
N’ígboyà mo súnmọ́ ìtẹ́,
Mo gba adé, lágbára Krístì.

**1. Àwọn t’ó m’Ọlọ́run, y’ó mú ọkàn le**
Nwọn ó j’alágbára lí ojú ìjà
Èyí n’ìlérí t’Ólúwa ṣe fún wa
Pe á ò ma ṣe iṣé agbára nlá wá

Ìṣẹ́gun, Ìṣẹ́gun
Ìṣẹ́gun t’a f’ẹ̀jẹ̀ rà
Ìṣẹ́gun, ìṣẹ́gun ni ojójumọ́
Jésù Balógùn wa, agbára wa k’yó yẹ̀.

2. Lárìn wàhálà nlá, máṣe sẹ́ ‘gbàgbọ́
B’agbára bí aṣẹ́gun n’nú iná ‘dánwò
Fi idà Ẹ̀mí rẹ ṣiṣẹ́ agbára
Fa ẹlòmíràn wá, sì yìn Olúwa

3. Jẹ́ alágbára, sì kọjújà s'ọ́tà
Ma yan bí aṣẹ́gun n'nú iná 'dánwò
Fi idà Ẹ̀mí rẹ ṣiṣẹ́ agbára
Fa ẹlòmíràn wá, sì yìn Olúwa.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Nípa ẹ̀mí ìsọtẹ́lẹ̀, mo pàṣẹ wí pé igi búburú ìyówù, tó n ṣiṣẹ́ láyiká ayànmọ́ mi yóò gba ifàtu lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo ibòjú òkùnkùn tó bo ògo ayé mi mọ́lẹ̀ yóò gba iná, yóò sì jó di éérú lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Lónìí, mo gbọ̀n dànù ohun ibi ìyówù tí àwọn ọ̀tá tó n ṣe bí ọ̀rẹ́ gbìn sínú àgọ́-ara mi, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde nínú agbára Rẹ lónìí, kí O sì mú ìdàrúdápọ̀ bá àwọn aninilára mi tó súnmọ́ mi típẹ́típẹ́, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá mi àti Olúwa mi, gbin àwọn ángẹ́lì ológun Rẹ sáyiká mi, láti túká àti ṣe ìparun fún ibi gíga búburú àjẹ́ abẹ́nú tó n yọ ayànmọ́ mi lẹ́nu, ní orúkọ Jésù.
6. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo pèníjà, mo sì parun gbogbo ìṣe sátánì tó lòdì sí ìgbé ayé àdúrà mi, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run, dìde, jẹ́ kí gbogbo ìfarahàn ibi láyiká mi túká lónìí, ní orúkọ Jésù.

## **ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ**

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.

2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Mo mú gbogbo ẹ̀mí ìdàrúdàpọ̀ tó yí ayé mi ká so nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo iṣòro (dárúkọ rẹ̀) tó n dúkokò mọ́ ayé mi, mo fọ́ ọ̀pá ẹ̀yìn rẹ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, jẹ́ kí ọ̀pá-ẹ̀yìn ọkùnrin alágbára tó wà nídì iṣòro kọ̀ọ̀kan má a fọ́ ọ́, ní orúkọ Jésù.
6. Mo pàṣẹ kí gbogbo ẹ̀mí atọpinpin ibi fimí sílẹ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.
7. Mo lo àṣẹ mi lórí àjẹ́ olóríkunkun, mo sì fa àwọn àgbékalẹ̀ wọn lulẹ̀, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**Orin Dáfídì 62:11:** Ọlọ́run tí sọ̀rọ̀ lẹ́kàn; lẹ́rìnkejì ni mo gbọ́ èyí pé: ti Ọlọ́run li agbára.

**Orin Dáfídì 89:13:** Ìwọ ní apá agbára: agbára lí ọwọ́ Rẹ, gíga li ọwọ́ ọ̀tún Rẹ.

**Orin Dáfídì 40:13:** Kí ó wù Ọ́, Olúwa, láti gbà mí: Olúwa, yára láti ràn mí lọ́wọ́.

**Orin Dáfídì 107:20:** Ó rán ọ̀rọ̀ Rẹ̀, Ó sì mú wọn lára dá, Ó sì gbà wọ́n kúrò nínú ìparun wọn.

**Orin Dáfídì 147:3:** Ó mú àwọn onírora àyà lára dá: ó di ọ̀gbẹ́ wọn.

**Orin Dáfídì 6:2:** Olúwa, ṣànú fún mi; nítorí àìlera mi: Olúwa, mú mi lára dá; nítorí tí ara kan egungun mi.

**Orin Dáfídì 103:2-5** Fí ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo ore rẹ̀: Ẹnití ó dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì; ẹnití ó sì tán gbogbo àrùn rẹ; Ẹnití ó ra ẹ̀mí rẹ kúrò nínú ìparun; ẹnití ó fi ìṣeun-ìfẹ́ àti ìyọ́nú dé ọ lí adé.Ẹnití ó fi ohun dídára tẹ́ ọ lọ́rùn: bẹ́nì ìgbà èwe rẹ di ọ̀tun bí ti idì.

**Orin Dáfídì 30:2:** Olúwa Ọlọ́run mi, èmi kígbe pè ọ́, ìwọ sì ti mú mi lára dá.